# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 571 SATURDAY, APRIL 4, 1964 (2D)


## Aṣoju Ijọba Gẹẹsi LỌ si Ipinlẹ Ila Orun

ẸNUGUN:- Gbogbo ebute ọkọ ofurufu lokunṣọṣọ ti ẹṣe ko si gba ero fun ọgunlọgọ awọn enia ti nwọn wa pade Ọlọla Francis Comming Bruce Aṣoju Ijọba Gẹẹsi ni Naijiria ati aya rẹ Iyaafin Gomming Bruce. Nigbati nwọn ba ọkọ ofurufu de si Ẹnugun ni ọjọ ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ keji oṣu yi lati ṣe ibẹwo ọjọ mẹta si Ipinlẹ na.

Gbogbo awọn Minista, Ijoye, Gomina, Alakoso Ijọba, awọn Oṣiṣẹ Ile Iṣẹ Ijọba Gẹẹsi ni Ipinlẹ Ila Orun ati awọn bọrọọkinni ilu lo wa pade Ọlọla na ati aya rẹ.

Onirohin wa ni Ẹnugun fi ye wa wipe, Ọlọla Francis Comming-Bruce ati aya rẹ ba Dọkita Michael Okpara, Alakoso Ijọba Ipinlẹ na jẹun ni ọsan ana. Nigbati o si di alẹ ana, nwọn ti lọ ba Ọlọla Francis Ibiam, ti iṣe Gomina Ipinlẹ Ila Orun Naijiria jẹun.

Ọlọla Francis Comming-Bruce ati aya rẹ yio ba ọkọ ofurufa de si Eko ti owurọ yi, nwọn o si tun lọ si Ipinlẹ Ariwa ninu ọsẹ ti mbọ yi.

# EJỌ OLOYE AWOLỌWỌ YIO BẸRẸ NI ỌSẸ TI MBỌ

## Oloye Amofin Ti Ilu Oyinbo De!

EKO:— Ni kutukutu owurọ ana ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi ni a ti tun bẹrẹsi gbọ hunnu-hunnu labẹlẹ kakiri gbogbo igboro ilu Eko pe ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ni ẹjọ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, olori ẹgbẹ Afenifere (A.G.) yio bẹrẹ ninu Ile ẹjọ ti o gajulọ fun orilẹ-ede Naijiria l'Eko.



ỌLỌLA A. ADEMỌLA
Olori Awọn Adajọ

Oniwe irohin wa ti o lọ si Ile-ẹjọ na ni iyalẹta ọsan ana fi ye wa wipe, ọsẹ ti mbọ yi ni ẹjọ Oloye na yio bẹrẹ.

Atipe, gbogbo awọn olupejọ na ni awọn alaṣe Ile ẹjọ na ti kọwe si pẹlu gbogbo awọn agbẹjọro wọn lati fi so fun wọn pe, "ọsẹ ti mbọ yi ni ẹjọ Oloye Awolọwọ yio bẹrẹ, ẹ ma amura silẹ o."

Onirohin wa kan fi ye wa wipe Ọgbẹni Victor Durand, ọkan ninu awọn ọjọgbọn oloye Amofin fun Ọba 'Binrin Gẹẹsi ti yio gbẹnuṣe fun Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ti de si Eko lana.

Ọgbẹni Durand ti kọwe bere fun aṣẹ Apapọ Ijọba lati wa ba gbẹnuṣe fun Oloye Awolọwọ ninu ẹjọ ti Ijọba mba ṣe. Apapọ Ijọba si ti gba fun agbẹjọro na lati wọ ilẹ Naijiria wa, ṣugbọn ẹjọ Oloye Awolọwọ nikan ni o le ṣe,

A gbọ wipe Ọgbẹni Durand nilati fi Orukọ silẹ ni Ile ẹjọ giga lati le fun un ni ẹkunrẹrẹ anfani, eyiti yio fi le wọ Ile ẹjọ Naijiria.

Ni Owurọ yi ni Ọgbẹni Durand yio kọ ṣe gbogbo awọn eto rẹ silẹ, ti yio ma a reti Ọjọ ti ẹjọ na yio bẹrẹ

A gbọ wipe Ọkan ninu awọn Ọjọgbọn amofin ti o yege lori Ofin awọn Arufin ati Ọdaran ni Ọgbẹni Durand iṣe, o si gba Ọpọlọpọ oye ninu ẹkọ imọ-ijinlẹ.

Nitori idi eyi, ọkan ninu awọn oludamọran fun Ọbabinrin Gẹẹsi ni Ọgbẹni Durand.



LATEEF JAKANDE



**Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ**

Oniwe irohin kan fi ye wa pe, Ọgbẹni Durand sọ pe, "Oloye Awolọwọ yio jare ẹjọ na, ti Apapọ Ijọba ba le gba mi laye lati wa gbẹnuṣẹ fun Oloye Awolọwọ."

Ọgbẹni Olu. Ayọọla, ọkan ninu awọn Agbẹjọro Ibadan ni o ti nṣe wahala lati le gbẹnuṣe fun diẹ ninu awọn enia ti Ijọba mba ṣejọ na ninu ile ẹjọ giga julọ.

Oniwe irohin wa kan ran wa leti pe, ni ọjọ kọkanla oṣu kesan ọdun ti o kọja yi ni adajọ Agba ile ẹjọ giga ọgbẹni G. S Ṣhowẹmimọ ṣe idajọ pe ki Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ o lọ si ẹwọn ọdun mẹwa oniṣẹ aṣekara pẹlu awọn enia mẹtadinlogun miran pẹlu rẹ.

Ni ọjọ keji oṣu na ni Oloye Awolọwọ ti pe ẹjọ kotẹmilọrun pẹlu awọn yoku rẹ ti Ijọba jijọ mba ṣejọ.

Ninu ẹjọ kotẹmilọrun ti Oloye Awolọwọ pe, o ṣe alaye lọna mẹrinlelọgbọn ti adajọ fi ṣi ara rẹ lọna.

Gẹgẹbi alaye Oloye Awolọwọ, o ṣe alaye pe, "adajọ ṣi ara rẹ lọna, o kọja iwọntunwọnsi"

Wo oju ewe kẹfa

# Ẹfufu Lẹlẹ Nki Nyin O

Ẹku aṣeyẹ Ọdun Ajinde. Ẹku ipamọra ọdun lẹnti nyin. Mo ki gbogbo nyin ẹnyin olutẹle Jesu lehin Emi ẹfufu lẹlẹ ti lọ bẹ awọn ẹni mimọ wo. Ẹnyin ọmọ enia mo mọ pe ẹo ti ma bere mi fun ọjọ mẹta Bẹni mo gbọ nigbati enyin nbere lọwọ Olotu ẹnyin ko ri Ẹfufu lẹlẹ. Nigbati mo ba kuro lọdọ nyin lọ si ọdọ Ọlọrun-igbadun wa lọdọ rẹ pupọ nitori pe ko si ohun buburu kan lọdọ Rẹ ati pada wa si ọdọ nyin nigba miran a ie ohun inira fun mi nitori iwa ẹṣẹ to wa lọdọ nyin.

Bi mo ti joko ti Ọlọrun legbẹ mo gbọ ohun ọpọ enia ti nwọn nyin Jesu logo fun ifarada Rẹ ijiya lori agbelebu.

Mo ri awọn ẹni mimọ nwọn nyi itẹ Rẹ kakiri awọn alagba mejila ini wọ aṣọ Ẹwa ogo wọn imọ-ọpẹ wa lọwọ won Eyi to jẹ ohun ami iṣẹgun iku Jesu lori agbelebu

IWA AGABAGEBE

Ha! Ẹwa Ogo na pọ to bẹ gẹ ti mo gbagbe lati yi pada wa wo awọn eni irapada ri Jesu ku fun.

Bi mo ti nwo ọdọ Agutan ini ni O ya ẹnu Rẹ ni ohun rara wipe Iwo Ẹfufu Lẹlẹ mura giri lọ si ode aiye lọ kilọ fun wọn ki nwọn kuro ninu ohun to lumọ ẹṣẹ

Bi mo ti nmura lati fo wa kuro niwaju Ọlọrun ni mo ri awọn Ogb logbo enia ti nwọn kunlẹ ni waju mi pe ki emi jọ ki nṣanu wọn lati bẹ wọn wa ojo kun ọlọ ori wọn

Mo rerin wọn titi fun iwa agabagebe ti o wa lenu awọn ọmọ enia Nwọn sọ pe ọdọ Ọlọrun dun pupọ nwọn ni ita wura Ọlọrun jẹ ita wura ti o dara yinrinyinrin ati pe ọdọ Ọlọrun mo bi kirisitali

Ṣugbọn bi emi Ẹfufu lẹlẹ ni ki nwọn ma bọ wa si ọdọ mi lọrun nwọn a bẹrẹ si tọ si ara nwọn pe ki nfi kun ọjọ ori nwọn

Eyi nkọ ọmọ enia? Ẹtan ko si niwaju Ọlọrun ọrọ agabagebe ko masi lọdọ Rẹ o di owọ nyin. Kini de

Ẹnyin ọmọ enia ariwo ibajẹ po larin nyin ifẹ owo po ai bọwọ fun ẹni bi Emi Ẹfufu Lẹlẹ. Ọlọrun ran mi si nyin pe ki e fi ara nyin fun adura pupọ nitori iku ojiji.

Mo ri ọpọ ni arọ ṣugbọn nko ri wọn mọ ni ẹlẹ Ki eyi ma ba si larin ẹnyin ayanfẹ rẹ ẹni lati fi ara nyin fun aawẹ ati adura pupọ.

IDARIJI ẸṢẸ

Bi mo ti duro ni agbede meji ọrun ati aiye lana ni mo ri awọn ọkẹ aimoye leti okun ti nwọn nse ajọyọ ti ọdun Ajinde. Mo ri awọn wundia kan nwọn nfi ibajẹ se ayọ.

Mo bere lọwọ okan ninu wọn ninu ohun kelẹ mi pe. kini eyi ti nwọn nse ini?

Mo wo titi nitori aṣọ to wa lara wọn ko bo ihoho ara wọn tan Bi mo ti nfọhun si ọmọ yi o dahun wipe ode ilaju ti awọn niyen.

Mo ni kinla, ilaju ati ba eranko dogba kọ nivi? Ko mo mi, o wo yi ka tit. Emi Ẹfufu Lẹlẹ tun fe lu ọwọ atẹgun mi fẹrẹ ka gbogbo aṣọ kuro lara rẹ.

Ayanfe kan wa nitosi. o lo yara kun lẹfun adura wipe idariji, idariji, idariji!!!

Bayi ni mo gba ẹbọ ti mo si fi wọn silẹ fun igba ayewo ẹṣẹ wọn.

GUGURU ATI EPA

Emi Ẹfufu Lele ki gbogbo awọn osiṣẹ Irohin Imọlẹ pe ki nwọn ku iṣẹ ati ifarada. Emi Ẹfufu Lẹlẹ fẹ ki nwọn fi ara balẹ ṣe iṣẹ dada nitori ọjọ ibẹwo mi ko pẹ ti emi yio wa pelu ere mi lọwọ mi.

Emi ko fẹ ri pe enikan ko gba ere iṣẹ rẹ ni ọjọ ti emi yio de. Bi Emi Ẹfufu Lele ko ba tilẹ mu o vo pupọ lọwọ ni ọjọ na.

O daju pe emi yio mu guguru ati epa lọwọ ni ọjọ na fun ipanu gbogbo awọn oniṣẹ ile Iwe yi. Mo ni reti pe Emi Ẹfufu Lẹlẹ yo ba olotu sọrọ ni ọjọ na. Sugbọn bọ ya ko le ri mi nitori eni airi ni mi.

Emi Ẹfufu Lẹlẹ nrele arebọ o! Tata o digb die o. Ajinde ara yo ma jẹ.

# Oluwa Rere Gba wa o

Lati Ọwọ ALHAJI Y. A. DISU

Ni gbogbo ọjọ ti a ba sun ti Ọba Alaanu si jẹ ki a ji dide ni ọjọ keji ni alafia, o tọ, o si yẹ ki a ṣe ọpẹ lẹkun fun Olusọ wa na ki a fo ṣe ohunkohun lọjọ na Ọlọrun ni ifẹ si ẹni ti o ba mọ oore, ti o si nfi iwa mimọ oore han. Ọlọrun ko ni ifẹ si iwa aimọ—oore

Agbọdọ ma a ṣọ ahan wa ni gbogbo igba ki a maṣe so isọkusọ si ara wa, ki a maṣe gberokero si ara wa.

Ọlọrun ko fẹ isọkusọ bi ẹja inu odo. Ki a ma si ṣe sọ isọkusọ si Edumare. Bi a ba sọ o, a o gba ẹṣẹ

GBALAGBA YẸ YẸ

Ọpọlọpọ afọwọfa ni a kọja mọṣalaṣi.

Awọn ọmọde na yio si fun wọn lesi ti yio wọ wọn ni akiyẹmi (eegun ati mudunmudu) ara.

ẸLẸṢẸ

Awọn agbalagba na nwọn yio wa abanijẹ, nwọn yio si ma a ṣe ileri si awọn ọmọ na pe, awọn yio fi oogun tabi tira ban wọn leemọ.

Nwọn koni laakaye, ifun wọn si sorikodo, nwọn si gbagbe pe Ọlọrun ju ẹnikẹni lọ, ko si si ẹni ti ko le mu.

Bi nwọn ba si ṣe oogun tabi sa tira na lọna aitọ, Ọlọrun ti ki i mu ni ti yio mu wọn, yio si na wọn. Ẹlẹṣẹ ki i yio silọ lai jiya ẹṣẹ rẹ.



Alhadji Y. A. DISU

IBẸRU ỌLỌRUN

Ẹ jẹ ki a bẹru Ọlọrun, ki a si ma a ṣe daada si ara wa Ika yio ka onika Melo melo ni awọn onisẹ buburu ti akiko ti kọ lẹhin wọn

Melo melo ni ojo ti o ti rọ ni ilẹ si ti fi mu. Ẹ jẹki a ma a ṣe ere ki a si ma a gbadura ni gbogbo igba, ki a si gbẹkẹle Edumare

Yio si kọ wa yọ lọwọ awọn elerokero, oninuburu oloribuburu kẹnimọni ati awọn obilẹjẹ enia. Oluwa rere: gba wa o, lọwọ wọn. Amin o.

nṣe, ti a si nsọ pe, Ọlọrun ni omu u wa Ẹlẹsan ko gbo oogun. Awọn agbaagba miran ti laakaye wọn sorikodo, ama a rẹ awọn ọmọde jẹ, a si ma a sọ isọkusọ si wọn lara.

Awọn ọmọde miran yio ṣe suuru fun wọn, nwọn yio si ma a wo wọn bi ọmugọ. Ṣugbọn nigbati awọn agbalagba na ko ba wa iyi ati ẹyẹ fun ara wọn, nwọn yio si gbe saata

Ẹ jọwọ, mo be nyin ẹ ye purọ mọ Olodumare mọ. Ọpọlọpọ iṣẹ ẹṣu ni ẹ npe ni iṣẹ Ọlọrun Eṣu ni o tan Judasi ti o lọ ṣe ijamba Jesu. Iṣẹ ire ni Ọlọrun nṣe fun wa.

Ki Ọlọrun o jẹki a le ma a ṣe iṣẹ rere nigbati iku ba si de ki ba ṣe ni ale tabi ni ọsan tabi oru ni kutukutu idaji ki o le ba iṣẹ rere lọwọ wa ki Ọlọrun maṣe wa ni ẹni Eṣu o.


## Akiyesi Pataki

A nfe Asoju ni awọn ilu wọnyi, Otta, Abeokuta, Ibadan, Iludun, Ololo, Agbọwa,-Ikosi Ikorodu, Ọyọ, Awẹ, Ilesha, Ẹde, Ikirun, Iwo, Shaki Iseyin, Tede, Oke Amu, Iganna, Omu-Aran, Ilorin Ajasse-Ipo, Iffọ Abalabi, Idọgọ.

Ẹkọwe si
Circulation Manager.
16, Gbamgbose Street.
Lagos.

# Oloye Kan Wẹwọn Ọdun Kan Abọ

KANO: - Oju gba gbogbo awọn ero ti o pejọ si ile ẹjọ kekere kan ni ilu Kano nigbati adajọ da ẹwọn ọdun kokan abọ fun Ijoye kan Dan Darman Isa ti işe Wakiliu Yama (olori fun awọn ti ngbe adugbo Iwọ Orun) ati awọn akọwe rẹ meji, Mallam Şhagari ati Mallam Daudu.

Esun ti nwọn fi kan wọn ni pe nwọn fi ọgbọn ẹwẹ jale ti nwọn si tun ko owo ori ti awọn enia abe wọn da ti nwọn si naa fun ara wọn.

Agbọ wipe Owo ti awọn mẹtẹta na ko je je din diẹ ni ẹgberun ponun (£946 : 10/-) ti si se Owo ori ti Ọpọlọpọ enia ti owa labẹ nwọn da fun Ọdun 1963.

Irohin fiye wa wipe Ijoye yi je owo Odun metaleladọta ati pe nihan bi Odun meji sẹhin ni nwọn fi ẹ oye naa.

Asi tun gbọ wipe awọn mẹtẹta na ti sọ pe ejọ ti nwọn daa awọn yi ko tẹẹ wọn lọrun.

## * YE IRAWỌ RẸ WO *

AQUARIUS (Jan. 21 - Feb. 19) Nitori ọna titun miran ti o fẹ bọsi laipẹyi yio mu ọna rẹ dara loni, awọn ọrẹ ati ojulumọ yio je onigbọwọ fun ọ jojọ pẹlu. iwa pẹlẹ di owo rẹ o.

PISCES (Feb. 60 – Mar. 20) Iwọ yio şe nkankan ti o ti ngbero lati şe, ki ilẹ ọjọ oni to şu. Şugbọn maşe ya ju si ẹnikan.

ARIES (Mar. 21 - April 20) Ma şe gbẹkẹle awọn to ba npun ẹnu fun ọ, opurọ ni won. Ibiti ẹkan rẹ ba dari si ni ko o ma a lọ, maşe jẹki nwọn o şi ọ lọna.

TAURUS (April 21 – May 21) Ọna ti o le gba fi ni owo, ko jina si ọ, bi o ba le ronu rẹ wo daradara loni, ọgbọn ju agbara lọ.

GEMINI (May 22 – June 1) Akoko to fun ọ nisisiyi lati mọ on ara rẹ, nitori alekun iranlọwọ ti Ọlọrun yio şe fun ọ laipeyi.

CANCER (June 22 – July 23) Pipe kan ti nwọn ma pe ọ lojo oni Lo ni jẹki o mọ iyi awọn ọrẹ rẹ. şugbọn maşe fi wọn şere.

LEO (July 23-Aug 23) Awọn ẹbi ati ọrẹ yio mu irohin aladun kan wa fun o loni. Ire ni irohin na yio je.

VIRGO (Aug 24-Sept 23) Ebi rẹ kan, yio fun ọ ni owo kun eyiti o ti ni lọwọ, ayọsi mbẹ fun ọ loni, ti o ko ba huwa igberaga.

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Ojo ti o fẹ rọ loni, yio gbe ibaje ọrọ ifẹ ti o ngbero lati ba obinrin kan sọ danu, maşe fi obinrin tabi ọkunrin na sile, Olufẹ rẹ ni.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Iwe kan ti oti nreti fun ọjọ pipe yio tẹ ọ lọwọ laipẹ osi gbọ irohin ayọ ati inu didun.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Owurọ oni yio mirigindin fun ọ bi oba ti i oja lati ra tete lọ raa loni, ere pupọ mbe fun o lati je şugbọn şọra ki oma ba lọ sọwọ awọn onijibiti

CAPRICORN (Dec 23-Jan 20) Obinrin kan ti o mbọ wa be ọ wo loni yio jeki ronu ti iWọ yio sun loni ara ọtọ maa fi oju si ọna, fun alejo kan.


# Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Yi Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ
Enikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe
"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ŞINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA t'Oluwa jọwọ şe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubori gbogbo ẹda patapata" Amin'

**"WAS SALAM"**

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo oye ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA
*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*
MANAGER
N2/99 SHITTU STREET
Ibadan



BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

*FUN*

**Lilo nibi Işẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

*ATI*

**Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IŞẸ ERỌ—ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboşe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ERỌ ITẸWE WA NHAN
*OWO PỌKU NI A SI NBGA*

IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa wo lẹẹkanşoşo ki o si ri iyatọ*



# Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara!

Awọn Egbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igboro ilu ko le şe Iwosan wọn lailai afi ki o ri ojulowo Egbogi "Ikọ" ti o ba lagbara gidigidi lati le hu Ikọ na lati ibiti oti joko si ti o si ti gbilẹ Fun awọn iru Ikọ bẹ yẹn bere fun egbogi wọnyi:

**"Thmo-Ephedrin" Tabi Egbogi 'Linituss'**

Fun iwosan ikọ Asma, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ikọ Igbẹdu, ikọ-ọnafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna ọfun tabi pelu kẹlẹbẹ tabi ti o ma nje ki enia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsan ati oru-gbiyanju lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara gidigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi şorokiti ti wọn nta kakiri.

O daju wipe iwọ yio bere si ri alafia, iwọ yio ma jẹun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yẹn Bere ni Şọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

# Nwọn Fẹ Ṣe Are Ẹyọ Adamu Orisa

Irohin ti gbojiikan kakiri Eko wipe, nwọn fẹ ṣe ere Adamu Orisa. Ere yi dun ni wiwo, ilu Eko ni kan ni nwọn ti nṣe ere yi. Nigbati nwọn ba nṣe ere yi orisirisi awọn orisa ati awọn Oloye ni yio ko Ẹyọ tirẹ jade

Nibẹ ni ao ri awọn orisa bi Adimu tabi Olumokun o si jẹ orisa to ni ẹru jojo ni agbo Ẹyọ ati awọn Abọyọ orisa yi buru, bẹni awọn Ẹyọ rẹ bọgiri.

Orisa miran ni Onikọ, omiran ni Ọlọgẹdẹ, Agere jẹ ọka ninu awọn orisa ti o mba Ẹyọ jade. Nitotọ orisirisi Agere lo wa sugbọn o risa eyiti o mba Ẹyọ jade

Gbọ bi awọn Ẹyọ rẹ ti nkọrin pe

Agere d'orisa
E gi to findan a ridan
Agere d'orisa

Ere Ẹyọ dun, o si dara ni wiwo sugbọn iba ohun to jẹ eriwọ fun enti o ba fẹ woran wọn gbadun, tabi bi o ba ri eyọ kan ti o mbọ wa, yara bọ salubata ẹsẹ rẹ kuro, ki o si si fila rẹ.

Awọn ara ilu oke ti o kọkọ wa si Eko ni Ẹyọ ti fi iya pupọ jẹ. Gbọ bi nwọn ti nkọrin lakoko na bayi wipe

Eko Akete ile ọgbọn
Arọdẹdẹ maja
Arọmisa lẹgbelẹgbẹ
Isẹkisẹ mbe lalakoro
Erukẹru mbe l' ẹhingbe ti
Gberu mi sọ mi, mbẹ l'odo Ọba
Ero to nre ile Eko, ko

bomi suru mu
Kurumọ a nani Aganyin a nani
Adamorisa apa oluwarẹ
Iagbọn atata.

Hu—u—haha 2

Nigbati o ba mba ẹyọ lọ sode, iwọ yio ma gbọ aroye lẹnu wọn. Diẹ ninu ohun nwọn nwi ni wọnyi

1. Alẹlẹ we ma le
Okunkun ma kun birimubirimu
Eniti ko mọṣe okunkun
Ko ma d'osupa loro
Hamọde Iraye
Hu u-haha

2. Emi a boju paa
Emi a boju wo o
Emi a bẹju lọmọ lẹru
bi orisa
Emi alegbada okiki
Ọkọ Sadatu
Hu - u haha

3. Asasa winrin, asasa winrin
Ewọn balẹ ro wọrọjọ
Lọjọ ti Akala nkala
Ti Aroko nroko
Li ayẹna nyẹna

4. Aroko ku a sinku aroko
Ayẹna ku a sinku Ayẹna
Awo lo ku loni
Ti a nsinku Awo
Ni mode Iraye
Hu - u - haha

# Ejo Oloro Pa Obirin Kan

AWKA:- Jinnijinni dabo gbogbo awọn ara ilu Awka bi irohin ti ntan kakiri ilu pe iya afin kan Oyilidi Dibua ti okọ ile rẹ si itosi ile orisa ti nwọn nbọ ni awọn ejo oloro pa bamubamu.

Irohin fi ye wa wipe Iya afin yi sun ninu ile rẹ loru ni awọn ejo yi ti nwọn le ni mẹdọgbọn ti nwọn si gunni nkan bi ẹsẹ mẹdogun mẹdọgbọn ya wọ inu yara rẹ ti nwọn si bẹrẹ si san titi o i ku.

Agbo wipe saju awọn ejo oloro wọnyi to pa obinrin yi ni awọn ara ilu ti ri awọn ejo oloro nwọn yi ni inu ile orisa yi ti nwọn si le ol risa yi jade.

Aborisa na difa le lori ti otun kilọ fun obinrin yi pe ki on ma fi abule tirẹ sile ki awọn ejo oloro yi ma bi ya a sile tire na.

Agbo wipe obirin yi kọ lati fi ile rẹ sile sugbọn nigbati ọd ni oru ojọ yi ni awọn ejo oloro yi ba ya lọ ba obinrin yi ninu ile re ti nsi kigbe titi ti ko si eniti yio gba silẹ titi ti ofi ku.

Bi awọn ara adugbo ti ri wipe awọn ejo oloro ni olọ ba a obinrin na ni nwọn ba sa pada ti nwọn ko sile wọ ile na ma rara.

# Igbimọ Atunto Ẹgbẹ imọlẹ Aiye

GẸGẸBI ati fi asẹ fun mi lati ọdọ awọn Igbimọ atunto ẹgbẹ Imọlẹ Aiye pe, nwọn ti tu ẹgbẹ Imọlẹ Aiye tẹlẹ ka, a si ti tun da omiran silẹ n torina ti o ba ri pe o fẹ jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ tẹ tun yi ki o kọwe si mi ki o si ri pe o wa si Ipade ni ọjọ kọkanla osu kẹrin (11/4/64) ni dede agogo mẹta ọsan.

Ẹgbẹ yi yatọ si ti atẹhinwa a si tun ti ni ofin titun miran, Eyi si ni awọn ere ti ẹgbẹ titun na yio ma ṣe'

1. Lati maa kọ awọn ọdọ ile yi ni ọna bi a ti nkọ irohin, itan, orọ sinu iwe Irohin lati ọdọ awọn Ojogbọn oniwe Irohin.
2. Ere bi Bọọlu alafese gba, Table Tennis, Swimming, Entertainment, Ayo, Isẹ, Draft Ludo Picnic ati ọpọlọpọ awọn nkan miran ti ọo ma a gbọ ni ipade.

Nitorina ti o ba fẹ tun jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ titun yi ki o wa si ipade ni ọjọ 11/4/64 ni nọmba 16, Bamgboṣe St., Lagos, Ao si tun yan awọn alaṣẹ ẹgbẹ titun

Eyi ni orukọ awọn Igbimọ atunto ẹgbẹ Imọle:—

1. J. Ọla. Okunlọla
2. Latifu Babalọla
3. Sedu Olupo
4. Abudulahi Awẹlẹnjẹ
5. Tmothy Akins

Ẹ jọwọ, ẹ tete de ipade o.


BERE OJU OWO EGBOGI AWỌN FARANSẸ TI NWỌN NPE NI- Eleyi yatọ patapata si awọn

# RICHELẸT

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO

Kọbi-rọbi. Isẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan ẹgbogi Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA bi Mon-mono

Mẹji rẹ ko si u gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TONIKI Eke ti nwọn si nti kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ aile ko di owo Iyen si ewọ, awa ki ta awọn egbogi bi won yen rara tabi ti nwọn npo ta ni ile yi.




Gẹgẹbi awọn Onibara wa i mọ irufẹ awọn egbogi ba won yen a ma a ba ọjọgbọwo egbogi atata ti a ranse fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Tatambulu si Itali je

Mo daju pe, bi eje ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju susu tabi didun, Jedijedi Ako iba, arun Edọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Eyi Amodi Apo ile itọ, ebin didun tabi ibaradi eiro pẹlu Egbon RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa nbe eje ara re patapata yio si n eje re mo tototo pe u.

Sa dan igo re kan wo iwọ yio si ma a rohin re fun elomiran pelu

Bere egbogi aejbina Richelet yi ni sọbu awọn Waterloo Medicine Stores 8, Palmchurch Street, Lagos Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LA WA

No. 571 SATURDAY APRIL 4, 1964 (2D)

## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lehinti mo ti se abewo kakiri Ile Naijiria ati Ghana, o dabi enipe opolopo enia ni nwon nro wipe Iwe Irohin Imole ati Iwe Irohin Akintola ti awon npe ni Imole Owuro okan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki ise be rara asi fe fi ye gbogbo enia ki o ye won wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imole daduro ko faramo egbe oselu kankan ko si ni ohunkohun se pelu Imole Owuro.

Iwe Irohin Akintola ti nwon nte ni Ibadan ni o ngbenuse fun egbe Akintola Ibadan ni nwon gbe nte Imole Owuro, Eko ni a gbe nte Iwe Irohin Imole lati odun n.e. (1957) sehin.

Ao se ifilo yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbo, sugbon eniti o ba tun fe alaye lori oro yi le kowe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Ise Irohin Imole ni nomba

16, BAMGBOSE STREET,
PHONE 21985, LAGOS.

# AWON TI O JA NITORI SISI, FI PONUN MARUN TANRAN

ILESHA:- Ha se gbogbo ero ti o pe jo si ile ejo kekere kan ni ilu Ilesha bi awon Olopa ti nka esun ija si awon osoro odomokunrin meji lorun ni ojo Isegun ti ise ojo kokanlelogbon osu yi.

Awon Olopa so pe Josiah Adesakin ti o nsise dereba moto pelu Alaba Adeloja berесi ja larin gareji moto nitori sisi (6d) lehin igbati Adedoja ati aburo re soka'e ninu moto ti Adesakin nwa.

Oga Olopa na Ogbeni Latifu Bakare so wipe bi awon mejeji yi ti sokale ninu moto ti nwon ba ko owo sile marun fun Adesakin ti nwon si tun bere si ipe ki o da senji sisi pada fun awon.

S gbon nigbati dereba na ko da owo senji sisi (6d) pada fun won ni nwon ba bere si ja ti nwon si lu ara won bi eni ma a ku.

Saju ejo yi ni awon odaran mejeji yi ti gba wipe awon jebi esun na.

Ninu idajo re adajo kotu na ni ki nwon losan ponun marun marun (£5) enikookan won.

O tun kilo fun won wipe nwon ko gbodo ja mo.

## Ejo Oloye Awolowo yio bere ni ose to nbo

LATI OJU EWE KINI

Irohin fi ye wa pe nigbati Ile ejo ti pari eda iwe idajo ti nwon fe lo ni Ilejo na nisisiyi, iwe mokanla ni Oloye Awolowo ra ninu re, Ijoba si gba egbeta ponun (£600) lowo re, ki nwon to le fun un ni iwe na.

Irohin fi ye wa pe, gbogbo awon Olujejo na ni nwon ti ra eda iwe kookan na sowo lati mo bi gbogbo ejo na yio ti maa lo.

Onirohin wa kan fi ye wa pe Apapo Ijoba Naijiria ti gba fun Oloye Awolowo lati gba Agbejoro wa lati Ilu Oyinbo ti o ba fe se be e.

Sugbon nigbati ejo na koko bere, ninu odun ti o koja, Apapo Ijoba ko gba fun awon agbejoro lati ilu Oyinbo pe ki nwon wa se ejo Oloye na, awon ti o pe nigbana Ijoba ko jeki nwon o wolu ti nwon fi da won pada.

Sugbon lana, Agbejoro Oloye Awolowo, Ogbeni Victor Durand ti de si Naijiria lati wa se ejo Oloye na.

Nigbati ejo na ba bere ni ose ti mbo, eo ma a gbo bi o ba ti nlo pelu orisirisi awon aworan.

## Fixed Odds Special

by:- POOL STAR

Perm any 3 from these:—
Chelsea
Bury
Swidon
Darlingtou
Hartiporls
Shaff Unitep

4 Aways Pools

Arsenal
Evertou
Preston
Chalton
C. Palace
Workington

2 Teams Failing To Draw

Blackburn
Liverpool
Tottehsm
West Ham
Cadiff
Leeds
Norwich
Portmouth
Bournemouth
Millwall
Oldham
Peterhorough
Carlisle
Watford
Southend
Aldersort
Bansley
Colchester
Halifax
Lincoln
Raugers

Special Naps

Sheff United
Man City
Motherwell
St, Mirreu
Derlington

Try your luck, this night be your lucky week.

## Kere o!

Fun anifan gbogbo enyin onisowo, Iwe Irohin Imole yio se ipolowo awon oja nyin fun nyin ni ose kan gbako ki odun Ileya o to de ati lehin odun ki awon onibara nyin le ba nyin ra oja ti odun Ileya ti mbo yi.

Awon Asoju wa yio ma a lo kakiri lati bere fun awon ti o ba fe lati polowo oja won ninu Iwe Irohin wa.

Owo pooku ni a ngba, dan wa wo lekan ki o si ri bi oja re yio ti ta to, Ijafara lewu o.

Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ALLOSUN 4, Kasali Street (C. M.S. Grammar School) P. O. Box Bariga (4/4/64)